# OKUN PUPA; IṢẸGUN ISRAẸLI LORI EGIPTI

**Ẹksodu 13:17-22; 14:1-31; 15:1-21**

**ẸKỌ 57 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹniti a ba mbawi ti o wà ọrùn kì, yio parun lojiji, laisi atunṣe" (Owe 29:1).**

**I Jijade Kuro Ni Egipti**

1 Ọlọrun mọ ailera awọn ọmọ Israẹli gẹgẹ bi ẹlẹran ara, o si mú wọn la aginju ja, Ẹksodu 13:17, 18; 14:11, 12; Orin Dafidi 78:39; 103:6, 7, 13, 14

2 Wọn ko egungun Josẹfu pẹlu wọn lọ, Ẹksodu 13:19; Gẹnẹsisi 50:25; Jọṣua 24:32; Iṣe Awọn Apọsteli 7:15, 16; Heberu 11:22

3 Ọlọrun fi ọwọ̀n awọsanma ati ọwọ̀n ina ṣe amọna wọn, O si pa wọn mọ́, Ẹksodu 13:20-22; Numeri 9:15-23

**II Ilepa Farao ati Ipo aini Reti ti o dabi Ẹni pe Israẹli Wà**

1. Ọna ti Israẹli gba mu ki Farao ro pe wọn ti ṣina ati pe wọn ti sọnu, ati pe eyi yoo si jẹ ki awọn ọmọ ogun oun fi wọn ṣe ijẹ, Ẹksodu 14:1-4; Numeri 33:1-8
2. Farao kabamọ dida ti o da awọn ọmọ Israẹli silẹ, o si lepa wọn, Ẹksodu 14:5-9
3. Awọn ọmọ Israẹli bẹru nigba ti wọn ri ẹgbẹ ogun Egipti, Ẹksodu 14:10-12; Orin Dafidi 106:7; Isaiah 31:1
4. Mose sọ ọrọ ikiya fun awọn ọmọ Israẹli, Ẹksodu 14:13, 14

**III Idasilẹ Kuro Lọwọ Ẹgbẹ Ogun Egipti**

5. Oluwa yẹ́ igbagbọ Mose si, O si paṣẹ fun Israẹli lati tẹ̀ siwaju, Ẹksodu 14:15, 16; Heberu 11:29
6. A ran idajọ iparun ikẹhin lati fi wiwà ati agbara ayeraye Ọlọrun hàn, Ẹksodu 14:17, 18; Orin Dafidi 106:7-12
7. Ọwọ̀n iná jẹ imọlẹ fun Israẹli, ṣugbọn o jẹ okunkun fun Egipti, Ẹksodu 14:19, 20; II Kọrinti 2:14-16; Johannu 3:18; Orin Dafidi 105:39
8. A pin omi niyà nipa agbara Ọlọrun, Ẹksodu 14:21, 22; Orin Dafidi 77:15-20; Jobu 26;10-12; Isaiah 63:11-14; I Kọrinti 10:1, 2
9. Awọn ara Egipti ti wọn jọ ara wọn loju rì sinu okun, Ẹksodu 14:23-31

**IV Orin Iṣẹgun**

10. Gbigbà ti a gbà Israẹli kuro lọwọ inilara Farao ni ikẹhin mú ki Israẹli ki o bẹru Oluwa ki o si yin In, Ẹksodu 14:31; 15:1-3; Orin Dafidi 66:5-7; Ifihan 15:1-4
11. Wọn sọ ti iṣẹ-iyanu naa ninu orin wọn ni kikun, Ẹksodu 15:4-10
12. Ifihan agbara Ọlọrun rú ifẹ wọn soke lati kọ orin iyin, Ẹksodu 15:11-13
13. Ninu orin yi ni a sọ asọtẹlẹ ohun ti yoo ṣẹlẹ sori orilẹ-ède Kenaani nipa iṣẹ-iyanu yi, Ẹksodu 15:14-16; Jọṣua 2:9-11
14. A fi idani-loju oju rere Ọlọrun hàn, eyi ti yoo maa wà titi, niwọn igba ti Ọlọrun yoo wà lae ati laelae, Ẹksodu 15:17-19; Isaiah 51:9-11
15. Awọn obinrin Israẹli kọ orin egbè, Ẹksodu 15:20, 21; Mika 6:4

## ALAYE

**Ẹsan Idajọ ti O Tọ**

Boya o dabi ẹni pe Oluwa kò gbọ́ adura awọn ọmọ Israẹli fun ọpọlọpọ ọdun ti wọn lo ni oko-ẹru Egipti. Ṣugbọn Ọlọrun ti fi omije awọn ẹrú wọnyi sinu igo ti Rẹ̀; nigba ti o si to wakati idajọ, esi de fun omije iyebiye wọnyi. Fun ọdun pupọ ni Egipti fi pọ́n Israẹli loju, ṣugbọn ọjọ ẹsan de nikẹhin. O dabi ẹni pe o pẹ, ṣugbọn o tọ nigba ti o dé. Gbese ti o wa nilẹ fun ọpọ ọdun ni iran ikẹhin yi san patapata, iran ti kò mú iwa ibajẹ baba nla wọn kuro, ṣugbọn wọn ni inu didun lati maa ba a lọ, ki wọn baa le gba èrè isinru-aṣa ti Ọlọrun kò fẹ rárá.

O dara ki a kọ ọgbọ́n ninu nkan wọnyi. Nigba ti ẹsan yoo ba de nitori iwa buburu, nigba miran ni idajọ naa maa n wá ni kikún sori awọn ti o kẹhin sidi ibi naa, ti won si pinnu lati maa bá ia buburu naa lọ bi o ti wu ki o ri. Jesu tẹnumọ ọn fun iran awọn Ju ti o wà ni akoko Rẹ̀ pe gbogbo ẹjẹ awọn olootọ n bọ̀ wa sori wọn, eyi ti a ti ta silẹ ni aye, lati ẹjẹ Abẹli olododo titi de ẹjẹ Sakariah ọmọ Barakiah, ẹni ti wọn pa laarin tẹmpili ati pẹpẹ (Matteu 23:35). A mọ̀ lati inu iwe itan pe, a mu eyi ṣẹ; ẹjẹ Jesu ti a ta silẹ ni a si ka si ọrun awọn Ju pẹlu, ni ipakupa ti a pa wọn ni akoko iparun Jerusalẹmu. Iyà yi ki bá ti jẹ wọn bi o ba ṣe pe wọn ti gba Jesu bi Messia wọn, ṣugbọn wọn kò ṣe bẹẹ. Awọn ara Egipti ti igba aye Mose i ba gbadun aye wọn ati aabo ti o daju fun ọdun pupọ bi o ba ṣe pe wọn ti bu ọla fun Ọlọrun Israẹli ki wọn si gbọran; ṣugbọn dipo eyi, wọn yàn ọna ibi.

**Ibẹrẹ Irin-Ajo Naa**

Ọna ti o lọ taara si Kenaani ni ọna okun ti o la ilẹ awọn Filistini já. Ṣugbọn iwe itan sọ fun ni pe awọn ọmọ ogun Egipti wà lọna ibẹ, ati pe ogiri nla kan wà lati Okun Pupa titi de Okun Mẹditareniani pẹlu. Bi o ba ṣe pe awọn ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo wọn pẹlu ogun jija si Ilẹ Ileri, boya i ba sú wọn, wọn i bá si ṣọtẹ si Mose ati Aarọni, wọn i ba si ti pada si Egipti.

Ki eyi ma baa ri bẹẹ, Ọlọrun mu wọn gba ọna aginju. Orilẹ-ède ẹrú ti a ko i ti ṣakoso rẹ ri ni wọn, a si ni lati fi ọwọ lile kọ́ wọn ni aginju, eyi ti yoo mu wọn yẹ lati jagun gbà ilẹ ti wọn yoo maa gbé, eyi ti awọn alagbara eniyan ti fi ṣe ibugbe tẹlẹ. Ọlọrun mu wọn gba ọna ilió, ki O ba le mu wọn wá sẹbá oke lati gbọ ohun Rẹ̀. Ọlorun yoo mu wa lọ si ọrun bi a ba tẹ le E, ṣugbọn Oun kò ṣeleri lati mu ni gba ọna ti o yá. Ohun kan daju: Oun kò ni mú wa gba ọna awọn "Filistini" tabi awọn ọna miran ti yoo yọri si iparun wa (Romu 8:28).

Bi o ba ṣe pe awọn ọmọ Israẹli ti gba ọna kukuru wọ Palẹstini wọn ki bá ti mọ rirì agbara Ọlorun. A ki ba ti kọ orin Mose. Harpu Miriamu i ba wa lai lo fi kọrin. Wọn ki ba ti ri Elimu pẹlu awọn kanga ati ọpẹ rẹ̀; wọn ki ba si ti mọ Sinai nibi ti wọn ti gbọ ọ̀rọ ifẹ ati ofin. Ki ba ti si manna lati ọrun wa fun wọn, wọn ki ba si ti mọsuuru ati ore Ọlọrun lakoko idanwo.

Awọn ọmọ Israẹli ni igbagbọ ati idani loju pe jijade wọn kuro ni Egipti jẹ titi lae ati opin irin-ajo wọn ni ilẹ Kenaani. Wọn fi eyi han nipa pe wọn mu egungun Josẹfu lọ pẹlu wọn. Ki i ṣe pe wọn fẹ lọ maa bọ ọ, ṣugbọn imuṣẹ ileri ti wọn ti ṣe fun Josẹfu ni pe a o sin egungun rẹ pọ pẹlu awọn eniyan rẹ.

**Ọwọ̀n Awọsanma ati Ina**

Oluwa fi ara Rẹ̀ han Mose ninu igbẹ ti n jò, O si fi ara Rẹ̀ han nisinsinyi fun Israẹli ninu ọwọ̀n ina ati awọsanma. Ogunlọgọ awọn eniyan wọnyi ti wọn tó aadọjọ ọkẹ (3,000,000) tan ka ọpọlọpọ mile ni pẹtẹlẹ ninu aṣalẹ ati lori gẹrẹgẹrẹ oke, wọn si n fẹ ami kan ti wọǹ le ri lati okeere. Ohun kan naa ti o jẹ ire fun awọn ọmọ Israẹli ni o ṣe idena fun awọǹ ọta eniyan Ọlọrun wọnyi. Nigba ti ẹgbẹ ogun Egipti sun mọ́ Israẹli ọwọ̀n naa wá saarin wọn, o si jẹ imọlẹ fun awon ọmọ Israẹli ati okunkun fun awọn ara Egipti. Ṣugbọn sibẹsibẹ Farao ati awọn ogun rẹ tẹ siwaju. Ko si ohun kan lọkàn won ti o le mu wọn naani ikilọ Ọlọrun. Aago ẹ̀ṣẹ wọn ti kún.

Awọn ọmọ Israẹli dabi ẹni ti o bọ́ sinu takute. Okun wa niwaju wọn, oke wa lọtun ati losi wọn, awọn ẹgbẹ ogun Egipti si wà lẹhin wọn. Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe igbagbọ́ wọn yẹ̀, igbẹkẹle Mose duro ṣinṣin. Lakọkọ ohun ko mọ bi Ọlọrun yoo ti ṣe gba wọn, ṣugbọn o mọ̀ pe Ọlọrun yoo ṣe e! A gbagbọ́ nipa ọna ti Ọlọrun fi ba Mose sọrọ, gẹrẹ ti o ti mú ki o dá Israẹli loju pe Ọlọrun yoo gba wọn, o lọ gbadura pe ki Ọlọrun le ki wọn laya. Ọlorun dahun pe "Eṣe ti iwọ fi nkepe mi?...tẹ siwaju," wọn si tẹ siwaju!

**A Pin Okun Niya**

A gbé ọpa soke, omi okun si pinya. Ará sán awọsanma si tu omi jade, ṣugbọn isalẹ oku si di gbigbẹ (Orin Dafidi 77:16-20). Wo bi iṣẹ iyanu ti ṣe e ṣe nipa igbagbọ́ ati igbọran pipe! Ṣugbọn ko si ẹni ti o le "tẹ siwaju" ninu agbara Ọlorun a fi bi o bá kọ "duro jẹ" ninu ailagbara ti rẹ na. Iṣẹ iyanu yi fi ibẹru si ọkan pupọ ninu awọn ara Kenaani, nitori a ka a wi pe ibẹru wa lọkan wọn sibẹ ni ogoji ọdun lẹhin eyi (Jọṣua 2:9-11).

Awọn miran ko ka itan lila Okun Pupa kọja yi si, nipa sisẹ iṣẹ iyanu ti n bẹ ninu rẹ. Wọn sọ wi pe iṣàn ti ko ga ati iji lile lori ibi ti omi kò gbe kún ni o làna silẹ fun awọn eniyan naa. Ṣugbọn a sọ gbogbo nkan wọnyi fun ni gẹgẹ bi iṣẹ iyanu ki i ṣe itan ohun ti o ṣẹlẹ, eyi ti a kọ sinu Bibeli nikan, ṣugbọn o wa ninu Orin Dafidi ati awọn orin iyin ti awọn ọmọ Israẹli n kọ lọjọ oni paapaa. Bi o ba ṣe pe iṣan omi okun lasan ni, ti ki i si i ṣe iṣẹ iyanu, Farao ati awọn balogun rẹ i ba mọ nipa iṣan omi yi ju awọn ọmọ Israẹli lọ. Balogun kan ko jẹ dari awọn ọmọ ogun rẹ lọ si ibi ti a o ti bori wọn nigba ti o mọ nipa iṣan omi ati iji. Ko ṣe e gbagbọ́ rara pe iṣan omi ati iji lasan le mọọmọ dá gbogbo awọn ọmọ Israẹli si ki o si pa gbogbo awọn ará Egipti run.

Idajọ Ọlọrun ni gbogbo eyi jẹ lori Egipti ati aanu si Israẹli. Awọn ti o ti ṣe ofin, ni ọdun pupọ sẹhin pe gbogbo awọn ọmọkunrin Heberu ni ki a ju sinu odo, awọn tikara wọn si parun sinu ọgbun ti wọn ti ṣe silẹ fun awọn ẹlomiran (Ẹsteri 7:10). Ọlọrun maa n san an fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ́ rẹ. Ifihan agbara Ọlọrun bayi ko le ṣai mu ki awọn ara Egipti gba pe Ọlọrun Israẹli ni Ọlọrun kan ṣoṣo ati Ọlọrun otitọ. Ohun ti wọn ko jẹ gba nigba kan ri lakoko ti Ọlọrun n fi suuru ba wọn lò, ni wọn ni lati jẹwọ rẹ ni wakati ti idaamu ikẹhin de ba wọn yi.

**Orin Mose**

Ohun ti o kọ́kọ́ jade lẹnu orilẹ-ede Israẹli ni orin aladun ti o bú jade lati inu ọkàn wọn, eyi ti a n pe ni Orin Mose. Bi o ti jẹ orin ọpẹ́ bẹẹ naa ni o jẹ asọtẹlẹ giga ti o n so ti jinnijinni nla ti iparun ogun Egipti yoo mu ba awọn orilẹ-ède ti o wà yikaa kiri gbogbo. O n sọ ti gbigbé ilẹ Kenaani lẹhin ọla, kikọ Tẹmpili ati ibi mimọ́ lori oke Sinai, ati ijọba oun isin Ọlọrun ti yoo maa wa titi lae.

Mose jẹ akewi ati olufun ni lofin. Ki i ṣe pe o jọ itan, ofin, ilana ati asọtẹlẹ nikan, ṣugbọn o ju ẹẹkan lọ ti o n kọ wọn lorin ti o kun fun imisi Ọlọrun. A sọ fun ni pe awọn Ẹni irapada yoo kọ Orin Mose ni ọrun (Ifihan 15:3). Ko si orin ayọ tabi ireti iye ti ko nipẹkun ni Egipti nitori pe aiṣododo ati aigbagbọ́ ko ni orin ayọ iṣẹgun ti iyin bẹẹ. Ọpẹ́ ni fun Ọlọrun pe O ti fun awọn eniyan Rẹ̀ ni ohun iyin ati ijọsin, ki wọn ba a le sun mọ Ọn si i, ki wọn si le wà

ni iṣọkan pẹlu ara wọn, nipa kikọ orin ayọ ti o ni imisi Ẹmi ati orin didun. "Ẹ kọrin si OLUWA, nitoriti o pọ li ogo: ati ẹṣin ati ẹlẹṣin li o bi ṣubu sinu okun."

**AWỌN IBEERE**

1. Eeṣe ti Oluwa fi mú Israẹli gba ọna aginju?
2. Kin ni egungun Josẹfu ti wọn mu kuro ni Egipti ja si?
3. Kin ni Oluwa fi ṣe amọna awọn ọmọ Israẹli ni aginju ni gbogbo ọdun wọnni?
4. Kin ni Farao rò pe o ṣẹlẹ si awọn ọmọ Isaẹli nigba ti o gbọ́ nipa ọna ti wọn gba lọ?
5. N jẹ awọn ara Egipti fi imoore hàn nigba ti awọn ọmọ Israẹli fi Egipti silẹ?
6. Kin ni awọn ọmọ Israẹli ṣe nigba ti wọn ri awọn ara Egipti ti n bọ wá?
7. Kin ni imọran ti Mose fun awọn ọmọ Israẹli?
8. Aṣẹ wo ni Ọlọrun pa fun Mose nigba ti o gbadura fun iranwọ?
9. Sọ ohun ti o ṣẹlẹ si awọn ara Egipti nigba ti wọn lepa awọn ọmọ Israẹli.
10. Nigba wo ni a ni lati "duro jẹ," nigba wo ni a si ni lati "tẹ siwaju?"